OWE

Oju ni a nmo aisi-epo, enu ni a nmo asiyo, ohe ti ko ni eran iduro ni amo.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

Asoje

Igbaliye, aiye ko l'ayele. B'ole loni o le re lola.

VOL. XIV No 819 LAGOS SATURDAY MARCH 3. — MARCH 9. 1962. KỌBỌ MEJI (2D)


# DOKITA CHIKE OBI, EWO L'EWO!! ISE L'OFE TABI ISELU ?

Irohin ta siwa leti wipe awọn Alaṣẹ Ile Ẹkọ Giga ti ilu Ibadan ti fi iwe kesi Dokita Chike Obi, ti iṣe Akonijẹ ẹgbẹ Dynamic Party ni ipinlẹ Ila-orun, ti o tun jẹ ọkan ninu awọn Olugbimọ Ile Igbimọ Aṣofin Ila-orun wipe awọn ti gba ki o lo isinmi oṣu mejila tabi jubẹ lọ lai gbowo oṣu, ṣugbọn ko gbọdọ le lọdun mẹta.



Awọn Alaṣẹ Ile Ẹkọ na sọ wipe ki Dokita Obi ronu ararẹ daradara ki o ṣe ipinnu lati fi ọwọ mu ọkan ninu iṣẹ iṣelu tabi iṣẹ Olukọni rẹ ti o nṣe ni ile ẹkọ giga na. O si nilati pada si Ile Ẹkọ Giga larin ọdun mẹta bi o ba fẹ ma a ṣe iṣẹ Olukọni rẹ ki o si yọwọ-yẹsẹ kuro ninu iṣẹ iṣelu.

Dokita Chike Obi sọrọ nilu Ibadan wipe "mo ti kọwe si awọn Alaṣẹ Ile Ẹkọ wipe iṣẹ iṣelu mi ti mu awọn ẹgbẹ Alakukọ (N. C. N. C) gbi'ja nitoripe nwọn kuna nipa eniti o alafia gb'oye imọ ẹkọ iwe."

Mo sọ fun awọn Alaṣẹ wipe ohun ti o wa niwaju mi pọ pupọ lati ṣe ti nkọ fi le jẹki a yi mi lọkan nipa alafia awọn to gb'oye ẹkọ iwe," eyi ti Ile Ẹkọ Giga ti ilu Gẹsi ti fi idi rẹ mulẹ.

Dokita Chike Obi wa nṣe apejuwe bi awọn ọmọwe ti o nṣe iṣe Olukọ nilu Oyinbo ti jẹ oṣelu ti ko di iṣẹ wọn lowe.

Ṣugbọn bi ilu Nigeria ti jẹ ilu ti o rehin, ako fe fi iyẹn fun awọn Alaṣe Ile Ẹkọ Giga.

## Adura Ti Ko To Suna

Mo bere f'eji
Oletu,
Ọpọlopo ena ni o ma ngbadura wipe "Ki Ọlorun fi owo se Ọrẹ wa", emi ko fẹ ki Ọlorun fi owo se ọrẹ t'emi.
Bi enikeni ba bimi lere ohun ti mo ri ti mo fi so bayi, emi yio la idi re ye won.

Emi ni
S. A. Majenrabun (Alias Ọfe)


**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**
Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA
ILARO, BENIN-CITY, WARRI
SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
15, THROGMORTON AVENUE, E.C.
Manager P. O. Tyrrell
Telephone : London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger : London
Head Office Representatives in London.
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK. PARIS HAMBURGH

CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENT
IKORODU TRADING COMPANY
20, & 28, Balogun Street, Lagos.

NO. 24.

**Federation Of Nigeria**
**THIRD DEVELOPMENT LOAN**

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £7 million registered Stock in February/March, 1962. The Stocks to be issued will be:—

1. £2 million 5% Federation of Nigeria Third Development Stock 1966—to be repaid in full on 7th June, 1966.
2. £5 million 6% Federation of Nigeria Third Development Stock 1986—to be repaid in full on 7th June, 1986.

Both Stocks will be issued in multiples of £10 at par, and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the Central Bank during the period 26th February to 26th March 1962.

Prospectuses, which contain full information, and application forms may be obtained from banks or at the Central Bank on or after 26th February, 1962.

W. A. TIBBLES
General Manager

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
FEBRUARY, 1962.

# OLE MERIN FI ODUN MERIN-LE-LOGUN GBARA

EKO—Nínú Kotu Genra (Asizes) ni Adajọ Dókítà Udo Udoma ti ṣa awọn ole ti o afi ohun ija egun jale si ẹwọn ọdun mẹrin-le-logun fun awọn mẹrin.

Awọn ọdaran enia merin na ni Kafari Yekini, Adeyemi Gbọlahan, Afolabi Adisa, ati Mutitola Abubakar, fi n ẹsun wipe awọn lọ jale nile epo mọto meta pẹlu ipa ninu osu August tokọja.

Awọn ole na fi mọto jale ni, awọn si ji owo £72 8: 9 ati igo omi didun merin-le-logun (mineral-Waters).

Adeyemi Gbolahan ati Afolabi Adisa, ọdun meje-meje, awọn meji yoku ọdun marun-marun.

Ninu idajo re, Adajọ sọ wipe Adeyemi Gbolahan nti o je omowe enia ni gbangbo ti o fa ese yi.

Lisdi Salu ti awọn mu mọ wọn ni Adajọ da silẹ nigbati ko ni eri to.

E ma se fomi sofo

DON'T WASTE



E ki Ic fun awon omo nyin ki won ma se fomi sere

ELETI-OFE D'ARABA

# ALASE ILERA NIGERIA MBA ALASE ILERA ILU OYIRBO SORO

Alase Ilera ilu Nigeria, Dokita M.A. Majękodunmi ni a nwo ninu aworan yi ti o ngbọ̀rọ lowo Alase Ilera tilu Oyinbo, Ogbeni Enoch Powell nigbati o lọ bẹ wo ninu ile işę rę nilu Oyinbo.



Dokita Majękodunmi yio şę abewo pupo si ile ikoşę Ile Iwosan ati ti St. Thomas ati Guy, tiawọn tun nřę Ile Iwosan mejeji siuju fun eye ẹkọ dardara.

Dokita Majękodunmi yio ba wọn sọrọ lori ile ikoşę Ile Iwosan ti ilu Eko ati ile ikoşe işegun ti a ngba lero silu Eko.

## Itan Eiye Aparo Ati Ejo

Ni ilu kan. A gbọ wipe iyan mu pupọ ni ilu nja ti ebi fẹrẹ pa awọn Eranko ti o wa nibẹ tan. Ilu yi jẹ ilu ti Ejo ngbe, şugbon ko si onjẹ fun won, Bi o ti di ojo kan ti ejo yi nwa onjẹ kiri, o ri apata nla kan o si ya sibẹ lati wa onje jẹ, Nigbati o de ibẹ o ri awon Era o si bere si jẹ won. Bi o ti njẹ won lowo laipe ni ojo nla kan bẹ sile, ni Ejo ni kini şubu tẹ on, o sare asala fun ẹmi rẹ nibiti o ti nsa asala lọ fun emi rẹ ori Ọgan kan ti iho wa nibẹ ko mọ ti yio gba wẹ.

Nigbati o wọ iho lọ tan, o ba Okete kan ti o ngbe iru iho yi nibẹ k'ama fa ẹrọ lọ titi, Okete na fi oju kan, Okete ni kini subu tẹ on, o iru rẹ şan ti şe baba on ri. Okete sare jade fun Ejo yi. Bi o ti jade ori igi kan ni ẹba rẹ kiapa o ti gun igi lọ. Igi yi jẹ igi Obi, igi igi Obi yi dahann wipe ohun kori Okete ni ode osan ri ni o ba binu yajọmọwọ rẹ kan iule.

(Wo yoka loju ewe karun)

**Always ask for 'DE FACTO'**
*the bread with the appetising flavour*

## OKU'JA WOLU

NIGBATI QJA KO BA TA, TI ENITI O RA QJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ŞE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIŞOWO LE SE TI QJA RE YIO FI MA TA

BI IŞU AKARA GBIGBONA.

**E Polowo Oja Nyin Sinu**

**Iwe Irohin Eleti - Ofe**

**Plushes, Velvet Velveteens**
**Damask & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

(63, Massey Street, Faji Market)

LAGOS NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.

# Onise-Owo yio Ran Ile Itoju Adete Lowo

Ogbeni Richard Turner ti a nwo aworan re yi ni okan pataki ninu awon Onise owo ti o ngbe igi ni bata so wipe on yio wa si ile Nigeria lati wa se iranlowo fun awon adete ni ile itoju won nilu Oji nitosi Enugu.



Ogbeni Turner s ro yi nigbati Dokita W.F. Ross wa be awon Onise-owo wo, ti o si soro lori inira ti o wa fun awon adete ti ko le wo bata . i .

# AWON ENIA SO SANGO DI ORISA

Loto ni Sango so, sso re na di itiju si awon ore re lara nitori yeye ni awon Oyo nfi Sango se

Nwon so itan kan, boya oto ni boya iro si ni nwon ni nigbakan awon ore re wa o n a k i awon ki enia wonyi ni ilo pe, ki nwon ma bu Oba mo ti nwon ba se kinikan: nwon lo si ile Ibariba nwon ko ogun ti enia le fi fa ara lati oju orun, igbati nwon de nwon beresi lo awon ogun yi.

Ara bere si san lu ile lemolemo, okan awon enia ko bale mo igbati won bere si wadi oran na ti o fi bo awon ore Sango bere si fonun wipe sango lo nsan Aara lati eju oran nitori yeye ti awon enia nfi isa, igbati Aara ba ti san, awon ore re aru bo sil nwon a si gba nkan lowo eni ti jirabi se nwon oni awon yio fi be Sango ki en ma ba bi nu sii mo ki awon se be gba oluware ninu iyonu.

Nira be oruko ti awon Oyo fun awon ore Sango ni magbe, oyo ti ira o no won si nje loni magba bayi ni awon enia siye igbana se nwon so Sango di Orisa ti nwon mbo titi di isisiyi.

Segbon ogbon sosoro wa ninu awon enia na nwon tilo w ako okuta ti ole ti o si yato si opolopo okuta miran eyi ni nwon npe ni edun Aara; bi Aara ba ti san, awon onisango yi arara lo, nwon abo okan ninu awon okuta didan yi mole ni apakan, Igbati o ba se ti nwon ti gba opolopo nkan lowo eniti Aara se ni jamba nwon a lo nwon a ma wa ile ibiti awon papa ti bo okuta na mo, nigbati nwon ba kan okuta na awon a mu jade edun Aara ni eleyi ni, eduro gegebi ota ibon ti Sango yin ni aiye.

( Wo yoku loju ewe karun )




# OLOYE EKO SORO . . .

EKO - Oloye Olumegbon, ti o je okan ninu awon Oloye marun ti Oba Adele fe ro Oloye ni a gbo wipe o so pe Oba ati awon Oloye re ko le ro on loye nitoripe awon ebi on ni on j'oye fun u.

Oloye Olumegbon so pe niwon igbati awon ebi on ba ti nfe on, on yio maa je Oloye Olumegbon ilu Eko, O tun tesiwaju wipe asiwaju Oloye ni on, awon baba nla on pelu ebi Oloye Aromire ni nwon te ilu Eko yi do.

'Awon ebi mi l'o fi mi joye niwon igbati nwon sinfe mi fila mi ko ni si "Beni Olumegbon wi.

A gbo wipe awon ebi Oloye mararun ti oro na kan se ipade ojule si ojule lati jiroro ona ti nwon yio mu oro na gba. A ko gbo bi nwon ti fori re ti si.

Alase Ilu Eko ko lati so ohunkohun nipa rogbodiyan na, a ko si le soro le.

# ALASE ISE ILERA NIGERIA NILU OYINBO



Alase ise Ilera ilu Nigeria Dr. M.A. Majekodunmi ni a nwo ninu aworan yi ti o mba Oloye nla Duke ti Devonshire soro nigbati o lo be ile ise Ajumosepo ti ilu Oyinbo nilu nla London laipe yi.

Alase Ilera ilu Nigeria, yio fi bi ojo meta yika Ile ise Ilera ti yio si ma ba awon Alase Ilera ti ilu Oyinbo soro pelu abewo ile ikose Ile Iwosan.

# Itan Eiye Aparo Ati Ejo.

Lati owo:- J. Olorun To Yin

Bi omo'owo re ti de ile ase oti pa omo Aparo marun, nigbati Aparo ti ode de, o ba igi Obi ti o ti ya lu omo re mole, laipe Aparo ti sare lo si odo Oba o ke ejo oro fun Oba, (1.) Aparo ni kabiyesi kade pe lori, ki bata pe lese, nigbati on wa rje lo, ki on to de Obi ti pa omo marun ninu omo on.

Lesekanna Oba ranse si Obi. (2.) Obi de odo oni kabiyesi kade be lori, ki bata pe lese, J je ni on duro si aye on, ki Okete to wa gun on ni inu ba bi on ti on fi va omo'wo on lule, lesekese ni Oba ranse si Okete, (3.) Okete ni kabiyesi Oba Oba toto bi aro, Oba rere bi osun. Inu ile ni on wa ki Ejo to to on wa, ni o mu on sa jade.

Lesekanna ni Oba ran on'se si Ejo (4.) Nigbati Ejo de odo Oba, o na tere, o ki Oba kabiyesi ki ade pe lori, nigbati Iyan mu ni ilu awon, on nwa onje kiri ni Ojo nla kan ba be sile, nibiti on ti nsa asala fun emi on ni on ba ri iho kan ni o ta rawo, oro on niyi o. Enyin Ojogbon, mo fe ki eba mi so eniti o ba jebi ninu won.

# AWON ENIA SO SANGO DI ORISA

(O bere loju ewe keta)

Sugbon og on s sor wa ninu awon eria na ti lo wa ako ikota ti ole ti esi yato si opolopo okuta miiran eyi ni won npe ni edun Aara: bi a pata ba ti san awon oi isango tora yi lo, nwon apo okan ninu awon okuta didan yi mole n apakar.

(Wo yoku loju ewe kefa)

# Itan Awon Omo Iya-meta

(O bere ninu iwe wa ose to koja)

Ni won ba mu ona ile pon won nlo nigbati nwon de Ilu kan ni nwon duro, nigbati ile su nwon sun nilu na be si ododun ni nwon nbo oju oba won, alejo ti o ba si wo ilu na ni won fi mbo ni nwon ba lo wi fun oba won pe awon alejo kan ti de awon si ti fun won ni ile kan lati ma gbe titi won yio fi lo.

Ni won ba nse won ni al jo ki nwon le ba lora daradara onje ati nkan miran ti awon Olola nje, eyi aburo ti o ko ise Oogun yen fura ogbe opon Ifa re lati mo ohun ti o wi, o si ri wipe won fe pa awon ni o egbon re ati abitele ati on papaa pe ewo ni sise ojo iku awon ti suumo etile, atipe ohun ti a le se ni wipe ki a bere ise gbogbo ti awon ko lati ma so nitori igbati awon ba sun ni nwon o wa ko awon ti awon ba si ba awon nibiti awon gbe asise, won ko ni anfani ati pa awon mo, ti ojo Ibogun won yio fi ye.

Ni gbogbo won ba nse won le, eyi ta'lor nran aso eyi aye ona bo si ona odi ilu won lati ma ye ona ti okun fun korlko, eyi aburo Ologun bere si sise Oogun orisirisi lati gba ara won la, T'osan toru ni egbon ti nran aso, ti awon olopa munimuni ba de mbo won aba loju ise, eru ade ba won fun ijaya ogun ti aburo won ti se fun akoya.

Nigbati orun sugbon sigidi Onibeta ti aburo won se awon meji ajoko eyi ti o to biju bi egbon awon okunrin yi ama aso lori masinni bi enipe oti ko ise na ri, ti awon olopa yi ba tun de, won a tun ba awon okunrin abiyewi sigidi yi lori Masinni laimo pe awon alejo yi ko ni awon ri.

# ERE IDARAYA BOLU AFE EGBA



Awora ti a nwo yi n ti awọn ẹgbẹ agba bọlu meji Wolverhampton Wanderers ati West Bromswich Albion ti nṣa bọlu afẹẹgba ṣere ije lori Ife kan ni Wolverhampton, England.

Awọn ẹgbẹ ti West Bromswich ni o bori ninu ere ije na pelu agba wọle meji si ọkan ti Wolverhampton Wanderers.

## Owon Omi Nilu Eko

Alase ise Ijoba Apapo ... ikilo lori omi ti ko ... fun lilo nilu Eko ... igbakugba, wipe oju iho inu fere ti ... ngba lati odo ogun wa ... inu ero omi Iju ni o ... pupo

O so wipe iho fere ti om... na ngba wa ti o kere ni ko ... ki o to fun lilo nilu Eko. ... ni o si ma nfa sababi tifo ti fe... re omi na ma nfo igbagbagbo.

Nitori eyi, nwon ti ... fere omi ti iho ... tobi, nigbati nwon ba si pari re, ko ni si iyonu fun omi lilo mo.

# AWON ENIA SO SANGO DI ORISA

(O bere lo'u ewe k ...)

Igbati o ba se t nwon ba ti gba gbogbo ọpọlọpọ ikan lowo enti apera se ni jamba nwon a lo, won a ma wa ile nibiti awon papa ti bo okuta na mo, nigbati won ba ken okuta na nwon a mu jade, ẹdun Aara ni eleyini oduro gegebi ọta ibọn ti Sango ... ni aiye, wọn biyi pe 'Oba Koso' etc. Awon Onisango ... oni gb kẹle Sango won gan. ki nwọn to jade ninu ile ti owuro pupọ ... won agbaduro si Sango won wipe ki ojo na le dara fun awon ki awon ma se ba jamba pade, ki awon lo si ibi ise awon tayotayo ki awon pada de tayotayo pẹlu. Nwon ama mi sere lowo nwon asi ma bu Ọla fun ẹdun Aara won. Nwon ni Igbagbo ninu re gidi-gidi. Nitorina e jowo e mase k'ẹgbẹ Onisango.

E jowo e mase k'ẹgbẹ ti ko dara nile aiye. E duro ti Ọlọrun Eledumare.

Eo tun ma gburo mi ni ese ti o nbo.

## Oko Ofe Fun Ero Meka

IBADAN - Awon Igbimo Alabojuto awon arin'rin ajo lo si Meka ati Medina ni ipinle Iwọ-orun fẹ ṣe iwe ọkọ-ọfẹ (ọko ofurufo) t'alo-t'abọ fun enia merin ti o ba fe lo si Meka ati Medina lodunni.

Awon Igbimo Abojuto awon ero Meka ni yio se gbogbo eto ise oko ofurufu ti ko fi ni si wahala fun awon enia merin ti o ba s'orire na.

Ikede na jade wipe gbogbo enti o ba fẹ lo si Meka ni odun yi, ki o lo ri akowe Igbimo nile ise Olotu Ijoba Iwo-orun nilu Ibadan ki esu yi to pari fun asepari eto.

# Eni Mejo Ku Opolopo F'arapa Ninu Jamba Moto

Benin—Enia mejọ ni a gbọ wipe o ku ti ọpọlọpọ enia si f'arapa ninu jamba a moto ti o sẹlẹ ni agbegbe ilu Benin.

Ni abule Nikorowa nitosi ilu Benin, enia meta ni nwọn ku nigbati ogi nla kan wolu mọto ti nwọn wọ enia meta ti o wa ninu moto kanna pẹlu wọn, ko ti le fi arapa ara.

Irohin miran tun sọ wipe ọkunrin kan ati obinrin kan ni nwon padanu emi won ninu jamba mọto kan ti o sele ni abule Opokuti nitosi ilu Asaba.

Ni abule kan ti nwọn npe ni Emu ni agbegbe Ishan ni omọkunrin kan ti o gun keke ologere mbo lati oko re ti kolu mọto eru kan ti o pa bambam.

Awamọto na ko tile duro wo.

Ọga Ọlọpa kan ati iyawo re pelu omo won okunrin ni nwon wo moto lati Agbo ti nwon mbo ni Auchi ti moto won sojude nwon ko awon meteta lo si Ile Iwosan ni Agbo, ko pe ti nwon de ile Iwosan ni omo won ku.

Bakanna ni moto pa obinrin kan si oju ona nigbati nwọn ... so mejo ilu Benin si Agbo, enia meje ni nwon ko lo si Ile Iwosan ilu Agbo ninu jamba meto ti o ṣele ni ona Ogwashi-uku si Isele-uku ni ọjo ose to koja.

Printed & Publihed By The Union Printing & Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 467 Phone No 23570